# AWỌN AMÍ MEJILA ATI IROYIN WỌN

## Numeri 13:1-33; Deuteronomi 1:19-24

### ẸKỌ 101 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: “Nigbati ọ̀na enia ba wù OLUWA, On a mu awọn ọtá rẹ̀ pãpa wà pẹlu rẹ̀ li alafia” (Owe 16:7).**

**Wọn Dé Eti Ilẹ Kenaani**

Awọn Ọmọ Israẹli ti de eti ilẹ Kenaani. O dabi ẹni pe irin-ajo wọn laaarin aginju fẹrẹ dopin. Ọlọrun ti ṣeleri ilẹ yii fun Abrahamu, Isaaki ati Jakọbu. Ni imuṣẹ ileri naa O ti mu awọn Ọmọ Israẹli jade lati Egipti wá pẹlu ọwọ agbara, lẹyin ti o ti bori gbogbo awọn ọta ti o doju kọ wọn.

**Ipese Ọlọrun**

Ọna ti là fun wọn laaarin Okun Pupa nigba ti o dabi ẹni pe ko si ọna kankan fun wọn lati lọ, ti ogun ọta si n lepa wọn bọ̀. Ọlọrun ti pese ounjẹ ati omi ninu aṣalẹ, ilẹ aginju; nigba ti awọn ara Amaleki si gbogun ti wọn, Ọlọrun ti fi iṣẹgun fun awọn ẹru alailẹkọọ ọmọ Heberu wọnyii. Ọwọ̀n awọsanma ni ọsan ati awọn ina ni oru ti n ṣamọna wọn fun ju ọdun kan lọ. Ọlọrun ti fihan nigba gbogbo pe Oun ni agbara lati fun wọn ni ohun gbogbo ti wọn n fẹ.

Akoko de wayii lati dá odi kọja bọ si Ilẹ Ileri naa, n ṣe ni o yẹ ki wọn kàn tẹle ọwọ̀n naa ki wọn si kọja lọ si ibi ti Ọlọrun dari wọn si. Ọlọrun ko ha ti ṣeleri ilẹ yii fun wọn bi? Oun yoo ha kọ̀ nisisiyii lati fi i le wọn lọwọ?

**Ẹṣẹ Aigbagbọ**

O ku diẹ gẹrẹ fun wọn lati ri imuṣẹ ireti ati àlá wọn, lẹẹkan si i awọn Ọmọ Israẹli tun ṣiyemeji Ọlọrun. Ẹṣẹ ti o tobi ju lọ ninu aye ni aigbagbọ. Oun ni gbongbo gbogbo iyoku. I ba ṣe pe awọn eniyan gba Ọrọ Ọlọrun gbọ, oye i ba ye wọn pe ọrun apaadi ni yoo jẹ́ ere ẹlẹṣẹ. Wọn i ba ri ijiya buburu ti yoo wà titi ayeraye ti yoo si jẹ ipin awọn ti wọn yipada kuro lẹyin Ọlọrun, wọn i ba si sure tọ Jesu fun aabo. Nigba ti eniyan kọkọ dẹṣẹ ninu Ọgbà Edẹni, ohun ti o fa a ni pe o ṣiyemeji Ọrọ Ọlọrun pe awọn o kú bi wọn ba ṣaigbọran si aṣẹ atọrun wa naa. Nitori wọn ṣe aigbọran si Ọlọrun, gbogbo iran eniyan di ẹlẹṣẹ pẹlu ireti igbala kan ṣoṣo: nipa Ẹjẹ Jesu ti a ta silẹ.

**A Rán Awọn Amí**

Ninu Numeri 13:2 Ọlọrun sọ fun Mose lati rán amí lọ si ilẹ Kenaani ki wọn le mọ bi ilẹ naa ti ri. Ninu Deuteronomi 1:22 a ri eredi rẹ̀ ti a fi rán awọn amí naa. Ọlọrun fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ gba Oun gbọ́ nigba ti O wi fun wọn pe o jẹ́ ilẹ ọlọra, ki ba si ṣanfaani mọ́ fun awọn amí lati lọ, ṣugbọn niwọn bi wọn ti n fẹ bẹẹ dandan, Ọlọrun gba wọn layè lati lọ wo ohun ti o wà ni Ilẹ Ileri naa.

Ọlọrun ti wi fun wọn pe ilẹ naa n ṣàn fun wàrà ati fun oyin. Ko i ti pẹ ṣaaju eyi, manna ti wọn n jẹ ti sú wọn to bẹ ti wọn fi kùn si Ọlọrun ti wọn si ti beere ẹran lati jẹ. Njẹ nisisiyii anfaani wa fun wọn lati lọ si ibi ti wọn o ti le jẹ oriṣiriṣi eso ati ẹran ati oyin ati wara. Ṣugbọn kàkà ki wọn gba Ọlọrun gbọ ki wọn si lọ gbadun ilẹ naa, wọn di ojo wọn si n fẹ ki ẹni kan lọ wo ilẹ naa lati ri bi wọn o ba le gbà a ni tootọ. Wọn ṣiyemeji Ọrọ Ọlọrun, si wo wahala nla ti o ṣubu lù wọ́n!

Ọlọrun ti ṣe awọn ileri nlá nlà fun wa; bi a o ba si fi ọwọ́ wa sinu ti Rẹ̀ ki a si gbẹkẹle E lai fiyesi bi nnkan ti n lọ fun wa, Oun yoo tọ́ wa lẹsẹẹsẹ. Oun yoo si mu wa wá sinu ẹkun rẹrẹ awọn ibukun ti O ti pese.

Ọlọrun jẹ ki awọn eniyan naa rán ami. Wọn yan ọkunrin kan lati lati inu idile kọọkan, ọkunrin ti wọn lero pe yoo jẹ ọlọgbọn ti yoo si mu ihin tootọ wá. Ṣugbọn mẹwaa ninu awọn ti wọn rò pé ó gbọ́n wọnyii kò ni igbagbọ kankan ninu Ọlọrun ju awọn eniyan iyoku lọ.

Lẹyin ogoji ọjọ wọn pada. Gbogbo nnkan ti Ọlọrun ti sọ, tootọ ni: ilẹ didara ni ti n ṣàn fun wara ati fun oyin. Ilu olodi ti ó ni ibugbe daradara fun wọn lati gbe wà nibẹ. Apẹẹrẹ eso ti wọn mu pada jẹ idi eso – ajara ti o tobi to bẹẹ ti eniyan meji fi ni lati fi ọpa ru u. Tilẹ ronu bi ilẹ ti o ni igi ati odò ati ọgba-ajara yii yoo ti dara to loju wọn lẹyin ti wọn ti n rin kiri laaarin aginju fun ju ọdún kan lọ!

**Ihin buburu**

Ṣugbọn ohun miiran wà nibẹ ju ẹwà ilẹ naa. Awọn eniyan n gbé kaakiri nibẹ. Awọn Hitti, ati awọn Jebusi, ati awọn Amori n gbe ori oke; awọn ara Kenaani si n gbe ẹba okun; awọn Amaleki pẹlu, ẹni ti wọn ti ba ja ogun kan ti wọn si ti ṣẹgun wọn, n gbe ni iha guusu. O dabi ẹni pe awọn amí naa gbagbe pe ninu ogun naa Ọlọrun ni O ti fun wọn ni iṣẹgun, dajudaju O si tun le ṣe bẹẹ lẹẹkan sii.

Awọn omirán si wà nibẹ pẹlu. Nigba ti awọn amí naa tẹju mọ awọn eniyan nla wọnni, wọn dabi ẹlẹnga lẹgbẹ wọn, ni oju ara wọn. Ṣugbọn a ha ni lati bẹru, bi wọn tilẹ jẹ omirán, nigba ti Oluwa wà niha wa? Nigba ti Dafidi jẹ

ọmọde oluṣọ-agutan lasan, o dá nikan bọ sita o ba Goliati ja o si bori rẹ̀. O ha mọ eredi rẹ̀? Bayii ni Dafidi wi fun omirán naa: "Gbogbo ijọ enia yio si mọ̀ daju pe, OLUWA kò fi ida on ọkọ̀ gbà ni la: nitoripe ogun na ti OLUWA ni, yio si fi ọ le wa lọwọ" (1 Samuẹli 17:47). Pẹlu Oluwa lọdọ rẹ̀ Dafidi le bi omiran naa wo lulẹ pẹlu okuta kan lati inu kànnàkànnà rẹ̀.

**Ogun Oluwa**

A le ri bi awọn Ọmọ Israẹli ba ti ṣẹgun gbogbo awọn ara ilẹ Kenaani. Wọn i ba ti jẹ ki Oluwa ja ija wọn fun wọn. Ọlọrun fẹ ṣe bẹẹ. Lonii yii Ọlọrun n fẹ ṣe bakan naa fun awọn eniyan Rẹ̀. Oun ko fẹ ki a ṣaniyan tabi ki a bara jẹ nigba ti nnkan ba ṣoro fun wa. O n fẹ ki a "duro jẹ, ki ẹ si ri ìgbala OLUWA" O mọ awọn iṣoro wa pupọ ju bi awa tilẹ ti mọ wọn lọ.

**Ẹmi Ti O Yatọ**

Awọn amí meji, Kalẹbu ati Joṣua, mu ihin ti o yatọ wá. Wọn jẹwọ pe, ni tootọ awọn ilu naa ni odi, ati pe omirán wa nibẹ; ṣugbọn wọn kò foya. Wọn wi pe "Ẹ jẹ ki a gòke lọ lẽkan, ki a si gbà a." Nnkan kan naa ni gbogbo wọn naa ti ri, ṣugbọn pẹlu oju igbagbọ awọn eniyan Ọlọrun meji wọnyii, ilẹ naa dabi ẹni pe o yatọ. Eyi ni iyatọ laaarin ẹni ti o ni igbagbọ lode-oni, ati ẹni ti kò ni igbagbọ. Idanwo kan naa ni yoo de ba awọn mejeeji; ṣugbọn bi ẹni ti kò ni igbagbọ tilẹ jọgọ nù ti o si di ojo, ọkunrin ti o ni ọkàn tootọ lati gbẹkẹ le Ọlọrun yoo wi pe, "Awa le ṣẹ́ ẹ."

Lati ọjọ pipẹ wá ni a ti n gbọ́ ninu itan Ijọ Ọlọrun pe iba "agbo kekere" Onigbagbọ diẹ ni o ti wà, sibẹ ẹsin igbagbọ ti la gbogbo akoko ọdun pupọ wọnyii kọja, o bori gbogbo agbara Satani lati pa á rẹ́. "Bi Ọlọrun bá wà fun wa, tani yio kọ oju ija si wa?" (Romu 8:31). Pẹlu Ọlọrun niha ti wa, a o sá maa ṣẹgun titi lọ ni, Ṣugbọn a ni lati jẹ ki Ọlọrun ja ogun naa ni ọna ti Rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1. Nibo ni awọn Ọmọ Israẹli dé?
2. O ti pẹ to ti wọn ti jade kuro ni Egipti?
3. Bawo ni Ilẹ Kenaani ti ri?
4. Ki ni ṣe ti awọn eniyan naa fẹ́ rán awọn amí jade lọ?
5. Ki ni iroyin awọn amí mẹwaa naa?
6. Lọna wo ni iroyin ti Kalẹbu ati Joṣua fi yatọ?
7. Njẹ nnkan kan naa ni gbogbo awọn amí naa rí?